ADURA FUN ỌSẸ YI

Jẹki ale san wa ju owurọ lọBaba rere

# IRAWỌ ★ OBOKUN

OWE ỌSẸ YI

Kise pe andi fili ẹtu Jasan ọsi ẹri ẹni- ti o'ba ẹtu jọ

Vol 3 No. 137 ILESHA. MONDAY. MAY 9 1955. IYE OWO: TỌRỌ

## ITESIWAJU ORILE EDE IJESA WA LOWO GBOGBO AWỌN ỌMỌ ILU



ALUFA MUSA BASIRI

On ni ẹniti gbogbo enia mọ ni Ọlọrun ni basiri on jẹ aburo fun Oloye Arapatẹ titun ti o jẹ laipẹ yi o si tun jẹ ẹnikan pataki ni Idile Sarumi

### ẸGBẸ ALAUUKỌ N. C. N. C. FAMỌYỌ

Lati Ọwọ Ọgbẹni J. O. Fadare "Alias Young Fad L. 73 Ifosan

Mo dupẹ lọwọ Olotu Irawọ Obokun fun aye ti o gbamilat ọrọ mi sinu iwe ọsẹ 'yi. Mo'k gbogbo ẹnyin ọmọ Ijes ni arin ilu ati ni ẹhin odi e ku ifarada gẹgẹbi aye ti nlọ yio

ẸGBẸ AKUKỌ FAMỌYỌ

Awọn ẹgbẹ Akukọ Famọyọ ni pa ibo ti a di ni Ilesa ati agbegbe tiẹ yi ka ni ai pe yi Ninu gbogbo awọn ti o dibo na larin igboro Ilesa o jẹ ohun ti o dun mọ mi ninu lati ripe awọn ọmọ Ẹgbẹ Akukọ lo bori na a si gbọ pe awọn ẹgbẹ ti nwọn npe ara wọn ni Afẹnifẹre subu ati pe owo iduro ti wọn ma nian silẹ ẹ'ọlọpọ ẹgbẹ na ni ko ni anfani ati ri ti wọn gba. Mo si ro pe awọn ẹni na yio ti mọ ara wọn!

NIPA ESO WỌN LA O FI MỌ WỌN

Njẹ awọn ẹgbẹ Ọlọpẹ ko nri oju aiye to de bayi bi Bibeli sọ bayi pe nipa eso wọn la o fi mọ wọn, nisisiyi gbogbo enia yio mọ pe nipa iwa aitọtọ awọn ẹgbẹ yi lao fi mọ iru ẹgbẹ ti wọn jẹ.

KINI ỌLỌLA KỌMỌLAFẸ ṢE

O jẹ ohun iyalẹnu fun mi pe awọn ẹgbẹ aturọla bi ẹlubọ yi nsọkun kakiri ilu ati agbegbe ilu wipe Ọlọla Kọmọlafẹ ko fẹran ia rẹ kini Kọmọlafẹ se? A ri ninu iwe ijọba Daily Times wipe ẹnikan ti a npe ni Akinsọla ti o npe ara rẹ ni olori alatako pe on le ki awọn se ọkọ Relowe de ilu bi marundogun nibu eyi ti Mile (ibusọ) rẹ yio jẹ ilọpo mẹta eyi ti o ti wa tẹlẹ bẹẹi ti a ba gbọ iyẹ owo ti eyi ti o ti wa tẹlẹ na ko le fẹnu sọ melo melo ni owo ti ilọpo mẹta be yio na Ijọba? Eleyi ni Ọlọla wa C. O Kọmọlafẹ sọ pe yio ko ti ijọba si igbeje ti a ba duro le o ni ti fi eyi ni silẹ ki wọn se ise mitun o ni od-ra jẹ

KINI ẸGBẸ ỌPẸ GBỌ EYI SI

Kini awọn ẹgbẹ Ọlọpẹ gbọ eyi si wọn bere si sọkun kiri pe asoju Ilesha ti lodi si ire ilu rẹ bi awọn abọpẹku Ilesha ti gbọ bẹni wọn wọn b rẹ si sọkun kiri bọ na ni iwe irohin wọn npuhun rere ẹkun pe Kọmọlafẹ ti lod si ire ilu rẹ

KỌMỌLAFẸ PẸ GEDE

Gbogbo awọn ọmọ Ijesa ki Ọgbẹni wa Ọlọla Kọmọlafẹ pe o ti i pegede ninu ile isofin ti Eko o si fa ọmọ yọ Awa ọmọ Ijesa si gba tayọtayọ durẹ lọwọ rẹ pe o ku ise ohun ti a ran lo jẹ ni Eko gẹgẹbi a se ran o. Mo si ti mọ pe isubu kole jina si awọn aturọla wọn yi.

Bẹrẹ ni oju iwe 5.



ỌGBẸNI E A SAJUYIGBE

On jẹ ọkan ninu ọgunagbongbo ti ẹgbẹ Alakoko N C N C ti Ibokun. O fẹsi si ọrọ kanselọ Akindele Ojo lose yi.

### EMMANUEL LANIYAN ṢE IGBEYAWO

(Lati Ọwọ J. O. Daradedi Ede)

Ni ọjọ kẹwa oṣu to koja ni Emmanuel Ọlaniyan gbe Julianah Adenihun ni Iyawo.

Irohin ko to afojuba ni ọjọ na, inawo na miringadin to bẹ ti o fi jẹ wipe Malu meji ni o subu sọnu ọbẹ. Tọmọde tagba jẹ ajẹyo ati ajẹti, ọti beer koni yẹ, ọti oyinbo ko ionka, bẹ si ni ẹmu ọpẹ. Inawo na dun to bẹ ti o fi jẹ wipe iru rẹ ko ti pe mẹta ni ilu Ara Ede

Awọn Ọmọge ti wọn se aṣẹyẹ ni ọjọ na ni wọnyi- Ruth Bimpe Esther Bimpe, Janet Oluwayọmi, Hannah Ojo, Susanah ati Gboyesọla pẹlu awọn ẹgbẹ Julianah Ọmọ Boya r'Daadodi.

Ogbeni J Abiọla Ogunrinde je ẹniji iyawo na gbẹru gan. Ẹgbẹ ikọmọ-dẹoku wa ati Ẹgbẹ Ọmọnagbẹhin Ẹgbẹ Olukọni (Teachers) The School Girls ati Ẹgbẹ awọn om Cocoa.

Awọn ti wọn mu ẹre se dun ni Ọgbẹni S. A. Akabi E. F. Ọbẹni, Abel Adeniyi, James Ojo Ajao Brox, Igbalẹja Boys, J. O. Daradedi ati Bamidele. Awọn Olusọla gbe Motor wa lati Sẹkuna

A ki ọkọ iyawo pe wọn ku inawo. Oluwa yio pese ọmọ rere fun iyawo na o Amin.

## IFILO PATAKI

Awọn Alakoso ile iṣe Ijesha Press Ltd. ni ki aṣẹ ifilọ yi fun gbogbo awọn ẹniti wọn da owo sinu iṣẹ yi yala ni ilu Ilesha tabi Idalẹ pe afẹ ki onikaluku ti akọtan orukọ rẹ ranṣẹ si Office Ijesha Press Ltd ni B.110 Okesha tabi P.O. Box 23 Ilesha.

Fun apẹrẹ ẹniti oba njẹ J. O. Aina afẹ ki o sọ orukọ ti J. O. duro fun, ki aba le fi akọtan orukọ yi sinu iwe ti ao fi ranṣẹ si onikaluku laipẹ yi.

Alabojuto

### ỌRỌ LORI IBUSỌ MOTO FUN ILEṢA

(Lati ọwọ E F Fadahunsi Si J 25 Ilẹmọ street Ilesha.)

Si olotu Irawọ Obokun Obokun agbe yin o mo tun se itati ọpọlọpọ iwe mi ti moti ko sẹhin nipa (garage) ibusọ motor ti ogbaru eyin ojẹ pe Ọna ati Ijoye fi ọwọ si ati Ajẹlẹ kekere ati Ajẹlẹ agba. Ọpọlọpọ owo ni awọn ẹgbẹ onimoto ti na si bẹ, bẹ na ni a tun gbọ pe awọ ijọba na tun na ọpọlọpọ owo sibẹ, papa ni akoko na ajẹlẹ agba fi yẹ wa pe on yio gbiyanju lati sa gbogbo agbara on nipa rẹ, akoko na ni angbọ pe awọn bi mẹta kan se awawi pe motor wọn tobi ona ibẹ kere. Lakoko na nkọ awọn ijọba bẹsi se titi ti olọ lati opopo ti oloye Lẹmodu lọ si ti idio wọn si bẹrẹ si to okuta si, wọn si se eyi ti olọ lati opopo Ifọfin ti osi jade si bakana.

Bakana ni ọna ti ọlọ si Padi jade si ibusọ motọ na awọn ọpọlọpọ enia ti ko tile de bẹ rara nsọ pe oke re bẹni ibusọ moto yi bẹrẹ lati adugbo titi de ọna ti olọ si padi. Gbogbo ibi yi ni a se dada fun awọn ijọba to fi ọwọ si pe ki ama lọ fun ibusọ moto.

Lẹhin eleyi, angbọ pe ọna Ijofi ni ama se si bẹna ni awọn kan nsọpe ọna odo-Iro ni, awọn miran ni oju ọja ni ama se si. Mo fẹ ki ẹro wo, eyi ti ijọba ati awọn ẹgbẹ onimoto na owo ati ara si ni oyẹ ki gbogbo wa fi ọwọ si ati na lọ.

Ibẹ tilẹ wa ni arin ilu osi jẹ arọwoto fun gbogbo enia lati ma wọkọ nibẹ. Ẹjọwọ ki ẹba mi to awọn ọrọ mi wọnyi ni ẹsẹsẹ ki awọn ẹnia le ri ka.

Obokun agbe yin o ona wọ ibusọ moto na lati Iroye Ẹrungbe, Okesha, ati ni ọna ilu oke nitorina gbogbo ọna lo wọ bẹ.

## ỌMỌ ẸRIMỌ Ẹ BOJU TO ATUNṢE ILU YIN

[Lati Ọwọ S. T. Ogundele NO. 68, Agbeni St. Ibadan]

Ni igbati atijọ bi enia ba wa ti kise ẹni ẹhin ti ki sise ẹni iwaju no mọ pe aiye okunkun niyẹn. Sugbọn ni aiye ode oni, igba ai- mọ ti kọja, papa ẹyin bi ọmọ Ẹrinmọ, Omi titun de Ẹja titun wọ inu rẹ emi gẹgẹbi ọmọ yin ti ẹ ti mọ tẹlẹ, se ẹ mọ oriki ba- ba mi bi bẹkọ emi o sọ fun iu nibe, mo si fẹ ki ẹyin na hijadu lati jẹ bẹ Baba mi lonjẹ AROWỌ MEJEJI KO ARA ẸHIN MỌRA

. o si ro wipe ẹyin na yio se gẹgẹbi oriki na ti wi o. Ohun t o mu mi sọ oriki yi nipe nigba aiye Baba wa ko si ohun kan ti wọn ba sọ wipe awọn yio se ti wọn ki se. Mo bẹ ẹyin Oloye ilu Ẹri- nmọ, ẹyin bi Risa-Ẹrinmọ; ẹyin bi Risinkin ti ẹ jẹ Orukọ Oye Baba mi, ti o si jẹ wipe Baba mi ni ẹ jẹ Oye tẹlẹ, atunse ilu Ẹrinmọ di ọwọ yin igba ni oni- gba nka, ofin ko mọ oju ẹnikan ofin ko mọ oju olowo, ki si mọ oju alagbara.

Mo tun bẹ ẹyin asoju titun, ile Ẹrinmọ di owo yin a ko fẹ ki apakan ma da ina, ki apakan ma fa sẹhin nitori a nwo yin gẹ- gẹbi bi ẹ ti nse; nitori ofin ko mọ oju ẹniti o se, ẹ ma jẹ ki a tan ara wa jẹ; ko si ẹniti o le ti ilu odikeji wa lati ba wa tun ilu wa se; ibajẹ olowo ibajẹ Onisegun awa Ọmọ ilu Ẹrinmọ ni ọmọ ibi ti o yẹ ki a tun se ni ilu wa ẹ jẹ ki a tete se atunse ilu wa ki akoko to kọja. Mofẹ ki ẹ wo iwe Ise awọn Aposteli ori ẹ ẹsẹ 19 ti o wi bayi, Nitori ọ ronu piwa da ki ẹsi tun yi pada ki ẹ le pa ẹsẹ rẹ ki akoko itura ba lẹ ti iwaju Oluwa wa.

Ẹyin ọmọ Ẹrinmọ atunse lopẹ ibajẹ kopẹ, ẹ wo akoko ti enia meji ti jẹ Oye Ẹrinmọ ẸLẸRINMỌ atunse sẹ di ọwọ yin. Awọn ilu miran jẹ Ọba ti wọn ko si ri- bi ti wa yi ati ẹmiran ti yanju ti wọn si ti yanju rẹ lẹhin ti- wa yiị Pupọ yin lo fẹ faramọ alatunse, pupọ ko si fẹ faramọ alatunse ka ka bẹ ibajẹ ni ọpọ- lọpọ nwa

Atunse ilu Ẹrinmọ di ọwọ yin ao wo bi ẹ ti sẹ ee asiko tiyin nlo Mo si bẹ ẹyin asoju wa ni- toripe pupọ ninu awọn asoju wa yi a ma se Osakasoko ẹniti o ba si ma jẹ osoko ki o jẹ ooko, ko gbona ko tutu ao po jade o. Ẹo tun ma ri iyoku ka ni o se o mbọ. Olotu mo dupẹ aye ti o gbami ọkọ Ọba koni sa ẹ ni ẹsẹ

## ỌGBẸNI MOJỌLA ANJỌRIN BẸ ILE ISẸ IJESHA PRESS WO.

Ni aipẹ yi ni ọgbẹni Mojọla Anjọrin wasi Ilesa osi bẹ ibi isẹ ile itẹwe ti Ijẹsa wo osi ba awọn osisẹ ibẹ sọrọ isiri pe ki wọn mura si isẹ wọn atipe irufẹ isẹ wọn yi jẹ iyin ati ọla fun ilu Ilesa, on na si ti pada si ibi isẹ rẹ ni ilu Sapẹlẹ.



ỌGBẸNI D. O. ẸNIỌLA

On jẹ ọkan pataki ninu awọn ọmọ Ijẹsa ti ongbe Ile Ifẹ on na jẹ ana si Oloye Abudu Arapate, on pẹlu awọn ẹgbẹ Alake Abanikanda si wa sibi asẹyẹ Oloye na ni ọjọ kẹrin oṣu yi.



ỌGBẸNI ALAKE ABANIKANDA

O jẹ ọkan ninu awọn Onisowo Motọ ni Ilesa, on ati ogunlogọ awọn Ẹgbẹ rẹ si wa sibi asẹyẹ ti Oloye Abudu Arapate ti ọse ijẹ Oye rẹ ni ọjọ kẹrin oṣu yi, awọn ẹgbẹ Alake yi si ṣe inawo pupọ nibẹ

## AKIYESI

FUN GBOGBO ỌMỌ ẸGBẸ NCNC-ẸGBẸ AKUKỌ

Afẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ NCNC mọ pe ipade ọjọ mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada: nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

## AKIYESI

FUN GBOGBO OMỌ ẸGBẸ ACTION GROUP ỌPẸ

A fẹ ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ Action Group mọ pe ipade ọjọ-mẹjọ-mẹjọ ti a nse ni Wednesday ko yi pada nitorina ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ fi sọkan lati ma wa si gbogbo ipade dede.

AKỌWE

## WANTED URGENTLY

Two Journeymen Printers to manage a press each

Apply in person

Adeniran Fowowẹ,

B 200 Oke Ẹshọ,

ILESHA:



KANSẸLỌ T A BABAJIDE

On je ọkan ninu awọn Oselu ti Ẹsa oke on na ni ẹniti wọn yan wa si Ipade nla ti Ilesa, ti a se ni ọjọ keji oṣu yi ni Gbọngan Obokungbusi, nibiti ati sọ ọpọ ọrọ fun ilọsiwaju ilu Ilesa.

## ABRAHAM FỌWOWẸMI ALASONIWỌLẸ DOLOCBE

[Lati ọwọ Adeniran Fowowẹmi.]

Ni arọ ọjọ Wednesday tise ọjọ kẹtadinlogun April 1955, ni dede agogo mẹfa owurọ ni Baba wa sun ninu oluwa. Lesekanna ni ogbẹni E. O. Fowowẹ, ẹniti o jẹ Daodu baba wa na si ti bẹrẹ si se inawo oku na ati awọn aburo re.

Baba wa yi ku ofi adọrin ọmọ olemeji sehin. Ninu wọn niyi E O Fowowẹ, Eliz Adedeji, J. A Fowowẹ, Kay ọde Adegoke Ọlawumi, Ọmọtọla, Adeniran Fowowẹ, Lalupekun ati ọpọlọpọ ti a ko le darukọ bayi.

Baba wa yi di ologbe bẹhin ti o ti lo ọgọrun ọdun ole marun laiye, ninu eyi ti o lo adọta ọdun ole meji ni Ipetu Ijesa.

Ati bẹrẹ si se inawo oku yi lati ọjọ ti o ti sun ninu Oluwa di oni ki ato ma lọ se awọn inawo ni Ipetu Ijesha gẹgẹ bi ẹ ti ri ka pe baba wa na ti lo adọta ọdun ole meji ni Ipetu.

Ninu awọn ẹgbẹ ti o wa si ibi oku ni awọn ẹgbẹ Iran lọwọ Club ninu eyiti ọmọ rẹ E. O. Fowowẹ jẹ ọkan pataki iasi dupẹ lọwọ ọga ile iẹwe ti Ijesa J O Awosan on na jẹ alabojuto eto gbogbo ti wọn se nibi isinku yi.

Baba wa yi jẹ ọkan ninu awọn ti o da isin Ọlọrun silẹ ni Ipetu Ijesha bẹni on si ni ẹnikinito okọ se isẹ asọ riran ni ilu yi, larin awọn ebi, ilu ore, aladugbo ati ijọ ako le gbagbe isẹ rere rẹ.

A ki gbogbo awọn ołuba wakẹdun ti baba wa ọmọd e ati lagba itan igbesi aiye baba wa di ọsẹ ti mbọ.

## ERIN WO NI ẸSA ODO ILEṢHA

Lati Ọwọ Jecob I Ogusturoti Faloye)

Ni dede agogo meje irọlẹ ọjọ Monde 4 4 55. Ọjọ kẹrin osu April ọdun yi ni okiki kan ni ilu Ẹsaodo pe Ogbẹni Faloye ẹniti ọjọ ori rẹ jẹ bi (132 years), Adoje ọdun ole meji ku, Baba yi si jẹ Alakikanju ati o ni wa rere larin ilu Diẹ ninu itan lailai ti a ma ngbọ ni enu rẹ ni wọn yi.- Ni akoko ogun nigbati Ogedengbe fi wa ni Balogun kekere (Captain) to fi lọ si igbo Akoko. on jẹ ọkan ninu ọmọ ẹhin rẹ; lẹhin igbati Ogedengbe dari ti igbo Akoko de to wa di Balogun nla (General) Baba yi wa di Asoju pataki nipa Iransẹ (Ambassedor) on di Asaju fun awọn ti Balogun ma nran lọ si igbo Addo lati lọ ra Ẹtu ati ọta wa fun on. Ba kanna ni Akoko ogun kiriji on ni aṣaju awọn to wa nra ohun ija ni igbo Addo, Nigbati o se ni akoko ogun Kiriji yi ọba Ọwa Bẹpo wa ni Ẹsa odo igbati o wa ngbọ okiki Baba yi ati bi o ti jẹ olotitọ ni o ba yan lati jẹ olori Ẹsọ. Nitori ni akoko ogun awọn ọba ama yan awọn ti o jẹ akọni si se olotito fun Ẹso ọba fun abo lọwọ ọta.

Lẹhin igbati ogun Kiriji pari ti aye si silẹ fun awọn ọmọ ogun lati ni obirin Baba yi fẹ obirin kini. Nwọn da ọjọ Iyawo fun, ki ọjọ iyawo to pe lojiji ni a gbọ pe iyawo na ku, o tun fẹ ekeji o tun se gbogbo ana bi ti iṣaju lojiji ni atun gbọ pe Iyawo na tun salọ igbati a wadi ọro na titi a wa ripe awọn Idile to jẹ Ọloja Ẹsa odo ni nwọn fi ọwọ sọwọ lati gba obirin wa

Igbati Akọda mu iwe Ikọsilẹ ti obirin na wale ko ba Baba yi nile o lọ si oko ọdẹ nitori ọdẹ pataki ni, awọn Lọja igbana fun Akọda igbana ni ọd (Cowry) ati didi oku ẹtu kan nwọn si kọ Akọda na pe ki o sọpe Baba yi lu on pe o si fa asọ Ọba ya mọ on lọrun Oke imọ ni ile ejọ wa ni akoko na igbati Baba yi gbọ to lọ si Oke Imọ Bi o ti de ohun ni awọn Akọda derẹ si fi odugbe Ibọn u lori (ẹdi Ibọn) nwọn lu ni ekini lori ati ekeji lori ẹkẹta to ba lori ko mọ ako ko to subu lujẹ igbati o si maji pẹlu sẹkẹsẹke lo ba lọwọ ati ẹsẹ rẹ Nwọn si gbe si ile tubu. Awọn ẹgbẹ rọ to gbọ nwọn lọ sọ fun ọga wọn Ogedengbe

Lẹsẹ kanna ti Ogedengbe gbọ ọrọ yi on papa lọ dide lọ si oke Imọ to pu Ajẹlọ igba na pe Ẹnyin fẹ fọ igbo yi? Ẹ gba obirin lọwọ enia ẹ tun gbe si itimọle. Ẹnyin Oyinbo ẹo kuku ba ilu yi jẹ ni dan? lẹsẹ kan na ti oyinbo igbana ti gbọ ọrọrbayi lẹnu Ogedengbe o sọfun awọn Akọda pe ki wọn lọda silọ Ẹjọ obirin Baba yi ni o lọ Akọkọ se Ẹjọ ikọsilẹ obirin ni Orilẹ Ede Ijesha Baba na tun fẹ gba obiri miran ni ilu keji si Ẹsa odo Obirin na gbe ọdun mẹrindinlogun lai ri ọmọ bi rara Obirin yi si fi silẹ laisan owo (dowry) pada fun lẹhin eyi lo tun wa fẹ obirin kẹrin Ẹkẹrin yi pẹlu se abibu ọmọ marun ki ọmọ to duro si lọwọ gbogbo enia fẹrẹ le ma sọ ireti nu fun pe ko jẹ nkan laiye mọ, sugbọn nigbati Ọlọrun bẹrẹ lati ranti rẹ lọjọ kan ṣoṣo Obirin meji to ni laya si bi ọmọ kurin meji gbo enia lo tun wo pe awọn meji yi fẹran ku na sugbọn Ẹda ko mọ pe kosi nkan to ṣoro fun Ọlọrun lati se

Diẹ ninu awọn ọmọ ti Ọlọrun fi ta Baba na lọrẹ ni igba Ogbo Aiye eri wọnyi Ogbẹni Samuel Oni Faloye
,, Michael Fabiyi ,,
,, Jacob Ogunturoti ,,
,, Isaac Awowale ,,



OLỌLA NAMDI ASIKUWB

On ni Olotu Ijọba Ile Oran og ni ẹniti o si se alaga nib ipade nla ti awọn ẹgbẹ NCNC se ni Ibadan laipe yi

E MA KA IRAWO OBOKUN

## OLOYE ABUDU SARUMI ARAPATẸ ṢE IJE OYE

(Lati Ọwọ J. O. Awosan

Lati owurọ ọjọ kẹrin oṣu yi ni awọn ẹbi, ọrẹ, ibatan ati awọn ojulumọ oloye titun yi ti nṣe imura fun ti inawo ti ije oye. Onikaluku awọn enia wọnyi lo si pese onjẹ silẹ lati fi se awọn ọrẹ, ati ẹgbẹ wọn ni alejo Oloye na si pa malu nla meji lati fi wa onjẹ fun awọn enia na. Bi awọn enia wọnyi ti nde ni angbe onjẹ ati mimu kalẹ niwaju wọn onikaluku wọn lo jẹ onjẹ ajẹti.

Ogunlọgọ awọn enia pataki losi wa lati awọn ilu bi Ilọrin, Ẹdẹ, Ifẹ, Osogbo, Ibadan, ati Eko lati wa ṣe ije oye na. Bi awọn enia wọnyi si ti mbọ ni awọn alejo pataki si ba wọn wa fun ati wa ṣe aseyẹ ti oloye titun na. Ogunlọgọ awọn ẹgbẹ pataki pataki lokunrin ati lobirin losi wa sibi aseyẹ yi.

Diẹ ninu awọn Ẹgbẹ ni Ẹgbẹ Alake Abanikanda. Ẹgbẹ Killa ninu eyiti oloye titun yi ti jẹ ọkan, Ẹgbẹ Asimowu Sarumi, Ẹgbẹ Ebun Sarumi, Ẹgbẹ Isiọla Ẹniọla, Ẹgbẹ Fisebililai obirin ati ogunlọgọ ti ako le darukọ tan.

Ki o ti to agogo marun ti oloye yi yio de ni ẹsẹ ogunlọgọ enia ti pe si afin ti gbogbo inu ile Ọba si kun tobẹ ti opo enia fi ni lati joko si ojude Gbọngan Obokungbusi. Bi Oloye yi ti ko oru Oye de afin ni awọn Ijoye ti o jẹ asaju rẹ ba ṣe atọna rẹ lọ siwaju Ọba Ajimọko ẹniti ọṣẹ asaju ni Oloye Adedeji Risawẹ pẹlu Oloye Awodiya Ọdọle wọn si dọbalẹ niwaju Kabiyesi on na si ṣe adura fun wọn Nigbati wọn si kuro niwaju Ọba tan ni wọn ba lọ bọ Obokun Bi ati pari awọn eto-yi ni Oloye yi ba pada lọ si ile rẹ bi o ti jade ni afin ni ibọn bẹrẹ si dun lọtun losi Awọn enia ti o wa sibi aseyẹ yi ju ẹgbaji lọ

Nigbati wọn si de ile onikaluku wọn si bẹrẹ si jo ijo aladun bi adapọmọ sẹkẹrẹ ati Agidigbo Irohin ko to afojuba aseyẹ ọjọ yi jẹ Akọle Olotu Aki Oloye Abudu Sarumi, Ebi, Ana, aburo, ọmọ ati awọn ọrẹ pe ẹku inawo, oye yio mọri o ki Ọlọrun jẹki ẹmi

Oloye gun fun ise ati alafia ilu Bi a ba jẹyi tan ao tun jẹ omiran si ajẹjẹ tun jẹ

Ire yio kari gbogbo wao:

## AWỌN NCNC ṢE IPADE NLA NI IBADAN

Lati bi ọjọ diẹ sẹhin ni ati ngbọ a ninu ẹrọ gbohungbohun ti a si nka ninu awọn iwe irohin pe awọn ẹgbẹ NCNC ti gbogbo ilu yio ṣe ipade nla kan pataki ni Ibadan. Ipade na si tobi pupọ ninu eyiti ogunlọgọ awọn enia pataki fi wa lati awọn ọpọ ilu ni Iwọ ati Ila Orun Naijiria.

Ọlọla Azikawe lo si ṣe alaga ipade na lẹhin ti o kuro lori aga ni Ọlọla J. O. Fadahunsi, bọ si aye rẹ lati ṣe akoso ipade na.



ỌGBẸNI E. FADAHUNSI

O jẹ ọkan ninu awọn onisowo Motọ ni Ilesa on ni ẹniti o kọ iwe ti o jade ninu ọsẹ yi nipa ibuso motọ ti Ogburu o si da laba pẹ ibọ dara pupọ fun ibuso motọ na.

## AKIYESI PATAKI

Ki ẹnikẹni ti o ba fẹ kowe sinu iwe Irawọ Obokun ma kọ orukọ ti on papa njẹ pẹlu adugbo rẹ. Toripe ọpọ iwe ni anri gba laisi orukọ. Eyiti ko basi ni orukọ ko ni tẹ jade.

ALABOJUTO



OLOYE S. ADEDEJI RISAWẸ ILẸSA

On ni ẹniti ojoko larin awọn ẹbi rẹ on jẹ ọkan pataki ninu awa agba Ijoye Ọba Owa Ajimọkọ On ni ẹniti o si Oloye Abudu Sarumi Arapatẹ wa siwaju Kabiyesi ni ọjọ ti nise ije Oloye titun na, ọba Ajimọkọ si ṣe adura fun Oloye titun na pẹlu awọn Ijoye ti o wa nibẹ pelu.

## ESI SI ỌRỌ AKINDELE OJO

[Lati Ọwọ Ọgbẹni E. A. Ṣajuyigbe]

Mo ri iwe Irohin ka ninu iwe Irawọ Obokun ti ọjọ kẹdogbọn oṣu April (25 : 4 : 55) lati ọwọ Ọgbẹni Akindele Ojo fun ẹsun apapọ ti o fun emi (E. A. Ṣajuyigbe) ati Ọgbẹni James Ọlarewaju Onibokun, ẹni ti nṣe ọkan ninu oṣiṣẹ Ijọba Ibilẹ ti Ijẹṣa (Dispenser) ati wipe Ọgbẹni Akindele Ojo tun sọ siwaju wipe on yio fẹ lati gbọ alaye lati ẹnu mi.

IPADE AGBEGBE

Nitotọ ni a da ipade kan ti a npe ni (IDC) eyiti o so pupọ enia pọ ni agbegbe Ileṣa, eyiti o jẹpe mo jẹ ọkan ninu rẹ ti Ọgbẹni James Ọlarewaju Onibokun yi jẹ ọkan ninu rẹ ti a si jọ nla niọ lati ṣe ipade yi ni nikibi ti a ba fi ipade na si, lati wa ire ilẹ wa ati anfani fun pupọ awọn enia wa pẹlu.

IPADE IJẸBU-JẸṢA

L'otitọ ni a lọ si ipade kan ni Ijẹbu-Jẹṣa ninu oṣu April, eyi ti mo lọ ti Ọgbẹni Onibokun na lọ pẹlu kiṣe wipe emi pẹlu rẹ lọ jọ rin, mo de Ijẹbu ni dede agogo mẹsan owurọ. Ibẹ ni mo si ba, nko si rope ẹtọ temi ni lati ma bere boya o gba iyọnda Ijọba tabi kogba iyọnda Ijọba ti o gba siṣẹ nitotọ Onibokun jẹ oniṣẹ Ijọba Ibilẹ Ijẹṣa ni, ṣugbọn kiṣe oniṣẹ labẹ Ọgbẹni Ṣajuyigbe.

Mo si mọ daju wipe ọgbẹni yi fun ra rẹ loyẹ lati se alaye lẹnu ara re bi o gba iyọnda tabi ko gba lọwọ awọn alaṣẹ ti a nsan owo oṣu rẹ.

EGBOGI NI ILE IWOSAN

Nipa gbigba egbogi ni Ile Iwosan l'otitọ ẹsun wasi etigbọ mi ni nkan bi oṣu mẹta sẹhin wipe ẹnikan ni on lọ lati lọ gba egbogi Iba lọwọ Ọgbẹni James Ọlarewaju Onibokun yi lẹhen ti on ṣe alaye fun pe ara on koda, on si fẹ gba egbogi Iba ni Ọgbẹni Onibokun wa sọfun pe kiniṣe ti on ko le lọ gba egbogi Iba lọwọ Azikiwe tabi Fadahunsi ṣe bi ẹgbẹ Akukọ ni on lẹhin ti ara-kurin yo mu ẹsun yi wa si eti gbọ mi mo si lọ ba Ọgbẹni Onibokun yi a sipari ọrọ na oni on fi basere ni mo si ti bawijọ o si dabi ẹnipe O gba ibawi na ni gbana. Ṣugbọn lẹhin eyi ọpọlọpọ wa lati fi ẹsun Iru kan na siwaju mi eyiti emi ko si bere mọ ti ti di ọjọ oni, ṣugbọn iru aṣa na nitotọ o mS ki pupọ ẹlomiran ma sa lati lọ gba egbogi ni Ile iwosan na

AGBODE GBA ẸGBẸ

Ni totọ ni ẹsun we lọ Ipetu/Ibokun wa lati ọwọ ọkan ninu awọn Oselu ibẹ wipe ni owurọ ọjọ na ni dede agogo mẹwa owurọ ọjọ ni Ọgbẹni:- James Ọlarewaju Onibokun yi wa si ọdọ wọn lati wa dẹru ba wọn wipe ti awọn ko ba kuro ninu ẹgbẹ alakukọ adanu owo ni wọn yio da fun ọdun mẹta ti ẹgbẹ Ọlọpa wa lori aga Ijọba yi, ṣugbọn mo fi ye oselu na wipe on fi eyi halẹ lasan ni ati pe papa pe ko si iru ọna ti o le mu gba ki wọn mase nkan ti o ba jẹ ẹtọ fun Ipetu Ibokun

Ekeji bakanna ni ẹsun wa lati Ikinyinwa pe wọn ko ni da ọda gba Ikinyinwa ti wọn ko ba se ẹgbẹ Ọlọpẹ tori wọn ko fẹ da ọda na gba Ilashẹ to ri ẹgbẹ Alakukọ ni awọn ara Ilashẹ nse, tori na iyoku kusi Ọwọ Akindele Ojo ati Ọgbẹni Onibokun.



ỌGBẸNI E A EKUNSEITAN

On ni Baba Ẹgbẹ N C N C Alakukọ ti Ijẹṣa, ogunlọgọ awọn enia pataki ninu ẹgbẹ yi lo lọ se Ibadan lati si ipade nla kan pataki laipẹ yi.



KANSELỌ B B MAKINWA

On jẹ ọkan ninu awọn ogunagbon gbo ninu ẹgbẹ N C N C Alakukọ ti ilẹ Ijẹṣa, Ogunlọgọ awọn pataki ninu ẹgbẹ na lo lọsi Ibadan lati se ipade.



ỌLỌLA OLU KỌMỌLAFE

On ni asoju fun Ileṣa ni Igbimọ nla ti Eko, on na si wa nibi pade ti ẹgbẹ N C N C ṣe ni Ibaidan laipẹ yi

## Ikede Ati Ipolowo Oja Ninu

## "IRAWO OBOKUN"

OJU EWE KINI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 8s. | fun inṣi kan. |
| Igba | 13—25 | 7s. 6s. | " " " |
| Igba | 26—52 | 7s. | " " " |

OJU EWE KEJI

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 5s | fun inṣi kan |
| Igba | 13—25 | 4s. 6d. | " " " |
| Igba | 26—52 | 4s. | " " " |

OJU EWE KẸTA

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 7s. 6d. | fun insi kan; |
| Igba | 13—25 | 7s. " | " " |
| Igba | ṭ6—52 | 6s. 6d. | " " " |

OJU EWE KẸJỌ

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igba | 1—12 | 6s. | fun inṣi.kan |
| Igba | 13—25 | 5s. 6d | " " " |
| Igba | 26—52 | 5s. | " " " |

OJU EWE 4, 5, 6, TI 7 JẸ OWO KANNA PẸLU TI OJU EWE KEJI.

## AKIYESI PATAKI

Afẹ ki awọn ọkawe Irawọ Obokun ni Ileṣa ati Idalẹ ma fi itan aladun Oloyinmọmọ ransẹ si Olotu Irawọ Obokun lati akoko yi lọ.

## ITAN OGBIGBO ATI ABIYAMỌ

Bẹrẹ lati oju iwe 6

ewure, ogota agutan, ọgọta ẹiyẹ ọgọta pẹpẹyẹ, ati ọgọ a igan aṣọ ti ja lulẹ siwaju obirin yi, nigba ti ẹiyẹ yi tun ke l.kera, wẹrẹ alẹgun kan lẹ o gbe ọmọ na si inu aṣọ aran nla kan, ọgọnlọgọ iranṣẹ lẹkunrin ati lobirin jade si obirin yi, nwọn ba ko gbogbo kaan wọnyi lọ si ile rẹ.

Nigbati obirin yi de ile, ẹnu ya ọkọ rẹ gidigidi, sugbọn inu iyale rẹ ko dun si rara. Nigbati obirin yi simi tan, o da gbogbo nkan wọnyi si meji—meji, o ka apokan fun iyale rẹ ati iyoku fun ara rẹ. Iyale buburu yi ba lọ fi ẹsọ wadi iọwọ awo rẹ bi o se di ọlowo, iyawo yi si so gbogbo rẹ fun patapata, ko ili pari bayi, o di ọsẹ to mbọ, e o tun ma gbọrọ mi o, enyin o kawe mi, E ku iṣẹ o, olọta Irawọ Obokun o.

## ẸRINWO NI ẸSA ODO

Bẹrẹ lati oju iwe 3

Arabirin Rachael Oni ,,
,, Dorcas Oni ,,
,, Alice Awotọla ,,
,, B. Fadọlapọ ,,
,, Alice Ogunshọla ,,
Mrs Olufumilayọ ,,
ETC

Oriki Baba ra ni yi Ọmọ Apoti Abidi rabakun, Ọmọ Adedigbo Ajo mẹrigun ọmọ oloko to Rinkoro kan oya, Igun Apado Ari jin nu nu ọmọ lẹnu ọmọ Asin Ẹrun lori, Eru ọmọ ari igbirin owo bọ ọdẹdẹ, Aida Adọdọ yẹgun ọmọ nṣe cri oko rijo-rijo ọmọ Ar ṣu bọja bi agbẹ ọmọ Ọlọyọ ru ya ki nwa pọn omi mo ba oji amu nibẹ Ọlọfa Baba Faloye jẹki mi pọn omi Sun reo!

## E KA NIPA IJỌBA YIN

Laipẹ yi, ilẹ Ijẹsa yio di ọkan ninu awọn ipinlẹ t o ni ijọba alajumọ-sẹpọ nipa nini igbimọ iṣejọba mejilelogun.

Wọn ni "bi egungun eni ba njo daradara, ori en a ma ya" Irawọ Obokun lero wipe yio jẹ idunnu ọlọkuluku lati ma ri irohin itẹsiwaju ka nipa igbimọ-ijọba akamọ tirẹ; nitoribẹ, a ti nṣe orisirisi atunṣe ni imurasilẹ lati ma ripe irohin njade ni ọsọsẹ nipa gbogbo awọn ijọba na.

Inu wa yio dun bi enyin okawe wa ati aṣoju wa ba fọwọsowọpọ pelu wa lati ripe iṣẹ na rọrun ni ṣiṣe.

Ọna ti e fi le ran wa lọwọ nipe:-

A fẹ Aṣoju (Agent) ni ilu kọkan.
A fẹ aṣoju si ni Ilesa.
A fẹ awọn ti yio ma fun wa ni irohin pipe.
A fẹ awọn Okawe kun awọn Ọkawe wa.
A fẹ ki awọn ti o mura tan lati ma ba wa sowo jẹ awọn ti yio ma sanwo lasiko.

**WANTED :-** IBODI LOCAL COUNCIL Invites Applicants for appointment as its Secretary. Applications to reach the Chairman, Ibodi Local Council c/o The Catholic Church Ibodi not later than 21/5/55.

MICHAEL FALỌPẸ, Chairman

**OSHUN LOCAL COUNCIL, IJEṢHA DIVISION**

Applications are invited for appointmet as Secretary to Oshun Local Council, Ijesha Division.

Minimum Education: CLASS IV·

Successful Candidate will be required to produce Two Bonds men. Applications to be directed to the Chairman, Oshun Local Council, c/o St. Paul's School Ilashe via Ilesha not later than 24th of May 1955.

S. P. OSUNRỌ.
Chairman.

**E polowo oja nyin sinu IRAWO OBOKUN**



ẸGBẸ IRANLOWO GBAJUMỌ CLUB

Ẹgbẹ yi jẹ ọkan pataki ninu awọn ẹgbẹ gbajumọ Ilesa, won si tun wa ninu awọn ti on wa itẹsiwaju ile Obokun pẹlu ogunlọgọ awọn ọmọ Ẹgbẹ yi lo si pesẹ sibi isinku Ologbe Abraham Fowowemi Alasọniwọlẹ ti asin oku rẹ ni aipẹ yi ni adugbo Oke Ẹsọ Ogbeni E. O. Fowowẹ tise Dandu baba yi jẹ ọkan pataki ninu awọn ọmọ ẹgbẹ yi

Printed and Published by Ijesha Pres Ltd., B110 & B149 Okesha Street, Ilesha 9-5-55